OWE YORUBA

Gidigidi ko mọla, k'asiṣẹ bi ẹru ko da nkan.
Ogbọn ko nitan ile aiye k'a wa lọ s'ọrun.
Eyi kotofo, eyi kotofo, fila Imale ko pẹrẹki.

ELETI OFẸ
A-NJU-WỌN KỌ ṢE WI L'EJO

Akiyesi Patakj

A fiwe yi ṣe ikede si awọn Asoju iwe irohin Eletẹ Ọfẹ kakiri agbaiye wipe, enikẹni ti ko ba fi owo ti o ti jẹ ranṣẹ si wa, ao pe lejọ, ako si ni fi iwe irohin ranṣẹ si enibẹ mọ.

VOL. XI No. 629. LAGOS, SATURDAY, JUNE 20, —JUNE 26, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Eran Agbo Di Yeye, Poun Kan Abo Wo Ileya.

APAPA. Gbanjo ! Gbanjo !! ẹran agbo ati Ogunfe ni okiki ariwo to gbojikan ni Apapa l'ẹnu awon ti o nta ẹran agbo, bi o ba tile ri owo diẹ san o le ṣe iwe fun iyoku.

Awon enia ti o ti kọkọ ra ẹran l'ọdunni ni o ra ọwọn, nigbati o di igbẹhin, agbọ wipe pọun kan si meji ti to pa ẹran ti o to fi pa Ileya.

AWỌN ONIDANỌ TUNDE !

A gbọ jugbanu irohin ti a tun ri gbọ ni wipe, awọn ero ti o wọ Mọto nlọ silu wọn lọ ṣe ọdun ni awọn Onidana ti o ma da awọn ọkọ ero lọna lati ko ẹru wọn, da Mọto kan lọna larin meji Ikorodu si Ijẹbu-Ode. Nwọn si ṣe ọpọlọpọ jamba fun awọn ero inu Mọto na.

A gbọ irohin pe nigbati nwọn da Mọto na duro, awọn fi ija p'ẹta nigbati awọn ogboju Ọlọṣa to nkole loju onile fẹ gba ẹru wọn lọwọ wọn, ti awọn ero inu Mọto na fi ake kọri wipe ko ni ṣe-ṣe. Kia ma fa ọrọ gun a gbọ pe enia bi mẹdogun ni nwọn fi ada ṣapa.

Ẹnyin ti ẹ nwọ Mọto rin loru, agba di ọwọ yin o. Jakunmọ ki irin lọsan ẹniti abire ko ni rin loru. Ẹṣọ ra yin o.

ọdun, ẹ ku iyedun, Ọlọrun ko ṣe ọdun na ni abọ ọdun fun wa, Ominira ti



ao gba lẹhin eyiti o mbọ ki Ọlọrun jẹki o ṣojn ẹmi gbogbo wa. Amin.

## Se Iranti

Ni Ojo Kini Osu July, Ni Owo titun Ti Ile Nigeria Yio Jade Fun Nina

## Gomina Agba Ki Awon Musulumi

Gomina Agba Sir James Robertson tilu Eko ki gbogbo awọn Musulumi lọkunrin ati lobinrin wipe ẹ ku



## Lagos Executive Development Board

# IKEDE

Diẹ ninu awọn enia lero wipe, nigbati Igbimọ Lagos Executive Development Board ba ti gba iwe eto ipin ilẹ fun awọn enia, nwọn ti gba wipe, awọn ti gba aṣẹ lati kọ ile na niyẹn. Rara o! Ọrọ ko jẹ bẹ.

1. Iwe ti a gba ti a fi pin ilẹ, fun ni laṣẹ lati pin ilẹ biri kan si kekeke, a si ti fi aye oju ọna moto sile. Ẹnikeni ti o ba fẹ pin ilẹ rẹ si wẹwẹ, yala fun tita, tabi fun ile kikọ, ki o wa gba aṣẹ lọdọ L. E. D. B., ki nwọn le yọ oju ọna moto sile.
2. Ẹnikeni ti o ba si fẹ kọle sori ilẹ tirẹ, ki eniti o ra ilẹ na tabi onilẹ paapa mu iwe ti o fẹ fi kọ ile na wa si ile iṣẹ L.E.D.B ki a ba le fi aṣẹ si yio tun mu lọ si Lagos Town Council lati gba aṣẹ ile kikọ pelu.
3. Nipa iṣẹ oju ọna ti L.E.D.B. Bi o ti wu ki o ri, apa ibiti a ti tunṣe, ti nwọn si ti ṣiṣẹ ọna ni ao gba pe ki a kọ ile si.

A fi eyi kesi awọn ti a to orukọ won nisale yi, wipe ki nwọn ṣakiyesi eto wọnyi ki nwọn to berẹ ile kikọ ti wọn.

| Orukọ | Ibiti ilẹ na wa | Ọjọ ti a yọda rẹ |
| --- | --- | --- |
| Adekunle Coker | Leti Teṣọn Relọwe ni | |
| S. B. Fasbanu | Surulere Plan No. C91/49 | 31-10-53 |
| Atitebi Family c/o | Surulere nitosi Western Ave. | 8- 9-53 |
| Body Lawson | Ọrọku Rd. Ebutemẹta West | 3- 4-54 |
| 35, Becroft St. Lagos | Plan. BL/9/54. | |
| Mr. Kojo Labelu | Isaga Road Surulere | |
| c/o Body Lawson & Lani- | Plan No. L & S/B 15 | 16-11-54 |
| yan, 35 Becroft St. Lagos | Idi-Oro | |
| Mr B. A. Ajetunmobi | Plan No. B.L/153/54 | 30- 8-54 |
| c/o Laniyan & Lawson | Ojo Oniyun | |
| 35 Becroft St. Lagos | Ebutemẹta West | 26-10-54 |
| Mr. J. O. Adenuga | Suru-Lere | 19-8- 55 |
| c/o Laniyonu & Lawson | | |
| 35 Becroft St Lagos | Suru-Lere nitosi Yaba Halt | 10- 1-56 |
| Mr. J. R. Vaughan | Igbobi. | |
| 27 Willoughby Street | | |
| Ebute-mẹta East | Igbobi Yaba | |
| Messrs F. Adeniran, | Plan No. B.L/83/54 | 8- 5-54 |
| Alamu ati Fasasi Adeyemi | | |
| 35 Commercial Ave Yaba | Iwaya Village | |
| Alhaji Yesufu Ajala | Plan No. C.T. 26/56 | 21-10-55 |
| c/o 35 Becroft St Lagos | | |
| Oloye A. A. Owodunni | Oroku Rd. Nitosi Abule | |
| 19 Inasa Court Lagos | O'o Omyun, Ebutemẹta West | |
| Mr. Isac Olughusi | Plan No. ASA 517A/56 | 26- 6-57 |

Igbimọ yio fi si ero, lati pese ilẹ miran fun enikẹni ninu awọn ti a to oruko wọn si inu iwe yi, bi a ko ba gba pe ki wọn kọle sori ilẹ ti a ti pin fun wọn nipa ilana awọn igbimọ ti wọn ṣe fun iṣẹ oju Ọna.

J. W. HENDERSON
Chief Executive Officer.

# ELETI - OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos.
CABLES & TELEGRAM "ELETI - OFE LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL XL NO 629. SATURDAY JUNE 20 - JUNE 26, 1959


# Alhaji Jubril Martin D'ologbe, Enire Lo!

Gbuke ni a gbo iku Alhaji Jubril Martin eniti ijoba yan lati lo se itoju awon ero ti o nlo si Mecca lati le Nigeria nilu Jedda.

Alhaji yi ni asiwaju awon Onise amofin ti ile Nigeria, o si ni Alaga fun awon Olotu ilewe Imale ati Baba egbe ijo Ahmadiyya. Ninu odun 1956, ni Alhaji Jubril Martin gba oye ise amofin (Lawyer). O si ti le ni odun mewa sehin ti o koko lo se Ahji tire ki nwon to yan ni ekeji yi.

Nigbati iro iku Alhaji Onisure yi tan kale t'omode t'agba, lokunrin, l'obinrin t'arugbo, t'emoge ni o ro lo sile ologbe na ni Opopo Bamgose,to fi kan awon Onidajo ati awon amofin ti nwon lo ba awon enia Alhaji kedun iku re.

Alhaji Jubril Martin ku faiye sile nigbati o dagba di eni odun mokanle-ladorin, enimimo ti Olorun, ki Oluwa gbe si afefe rere.

## OJO KAN KO DUN BI OJO KEJI ILEYA

Afi woaka wa yi ki enyin ore wa Musulumi ku ewu odun Ileya, e si ku pedun, ki Oluwa se odun na l'abo odun fun gbogbogbo wa. A ki gbogbo enyin ekawe wa, ni Kirsiyo tabi Onigbagbo. Imale ati eleśin miran ku ewu odun bakanna, nitoripe gbogbo enia odun ba ti de ba ni yio yo ayo odun titun.

A ni "Ojo kan ko dun bi ojo keji Ileya" ati Musulumi ati Onigbagbo, papa gbogbo wa ni o mo igbadun to fa owe yi wa, nitoripe, bi ko afi eran dindin pa'nu tabi ki afi obe didin je bute-de — ko ni won enikeni.

Barika de Sallah.




No. 97

# Government Statement On The Claim By Ex-Servicemen For Two Shillings A Day Arrears Of Pay

On a number of occasions groups of ex-servicemen have made claims for two shillings a day arrears of pay alleged to be due to them in respect of their service with the colours.

These claims are based on a wrong reading of Army Order No. 78 of 1948, which authorised the payment of arrears, dating from the 1st April, 1946, to men who enlisted on or after that date in the *Pioneer* Corps (High Commission Territories). This corps was raised in 1946 in Bechuanaland, Basutoland and Swaziland. It was quite distince from the African Pioneer Corps and from all other army units. The arrears were paid because the corps was at first granted only interim rates of pay which were later found to be inadequate when compared with civilian rates in the three High Commission Territories.

Many ex-servicemen have wrongly been led to believe that the rates paid to the force recruited after the war in the High Commission Territories were applicable generally to men enlisted in Nigeria and that they were back-dated to include war-time service. This is not the case. They were applicable only to men who enlisted after the war in the Pioneer Corps (High Commission Territories) and even in their case were effective only from the 1st April, 1946.

Claims to the arrears by Nigerian ex-soldiers are thus inadmissible and their recurrent submission by the leaders of various ex-servicemen's associations can only lead to disappointment.

Ministry of Internal Affairs.
Lagos.
10th June, 1959.


ARA-O-LIN - IPARA ATATA




ARA-O-LIN je ipara ti o gbamuse. O tayo gbogbo irufe egbogi bee ti o ba l'oja. O dara fun lakuregbe, egbedidun, aran-latanlatan, ehin-didun, ibaradi-sise, arinka-inu-egun ifo apa tabi ese ro, efori, iulu, otutu-aiya, otutu-agbari, ikun-didimu, orun-didun ati orisirisi aisan kungekunge bawonni. Nitori werevere ti o nta, awon Yoruba npe e ni "ATA", Ibo npe e ni "OSE" Hausa si npe e ni "BOROKONU". Dan igo kan wo ni 2s. 6d. (oto l'owo-oko) lati mo bi o ti ri.Kosemani ni.

**The Egba Trading Aradan Stores,**
16 Denton Bridge St., P. O. Box 2, Ebute-Metta.


# ILORIN KO NSE HAUSA

ILORIN Ogbeni J.G. Ekunrin, okan ninu awon Olugbimo fun ile Igbomina ti ile Hausa so pe, ko nse ohun ti o le tobe ni oro Ilorin fe fi aramo Yoruba tabi ko fi ara mo Yoruba enikeni mo daju gbangba pe Ilorin ko ni ilosiwaju kan awon egbe N.P.C. lo si fe baa je, ko si ohun ti o dara bi wipe ki Ilorin pada si ile Yoruba nibiti awon omo iya wa yio koya fun wa.

Ki enia so pe Hausa ni yio gba wa kale regerege iro ni ko nse awon Hausa. Gbogbo enia dahun pe, Olorun ma je a yafi Yoruba omo iya wa ni yio sin wa titi de ile na ti o san fun wara ati fun oyin.

## EniKan Mbere Oro Lodo Oyinbo Elepo (Shell BP)

IBERE. Nje bi e ba fe gbe ile nibikan lati wa epo ninu ile na, ti nwon si so fun nyin pe, orişa won lo ni apa ibe. Kini ohun ti enyin yio se bi nwon ba ko wipe, e ko gbodo gbele nibe?

IDAHUN. Bi oro na ba ri gegebi e ti wi yi, ao ba awon to ni orişa na soro ni itanbi-itanbi bi yio ba şeşe ki nwon gbe orişa won lo si ibomiran, bi nwon ba ba si nfe owo lati fi se etutu isipo-pada tabi lati fi bo orişa na ki o jowo fun wa ni aye nibiti o gbe wa nitori a ni ibe lo.

Bi nwon ba taku patapata, ao ko eru ati irinşe wa lo siwaju ibiti ao le beşe işe wa, ti a ko ni de sakani orişa na.

Şugbon sa! a koiti ba iru atako bayi pade lati ojo yi wa. gbogbo awon enia ni o ngba fun wa nigbati a ba ti le fun won lowo lati fi se etutu na.

IBERE. Kini yio sele ngbati onile ba taku wipe, oo ko fi ara mo oro ti Aşoju ati oyinbo shell ba ara won so lori iye owo ti nwon fe san fun ile ti nwon fe gbe na.?

Nitori ki a le gbele fi wa epo moto ni a se nwale ti. Ijoba ba ti fun wa ni aşe lati ma lo ile na, nipa aşe Gomina Agba ati awon igbimo re.

Gegebi nwon ba ti ro o si, awon ni yio so iye owo ti o to ki a san fun ile kan. Ao si san owo na le Gomina Agba lowo titi awon enia ti o ni ile na yio fi wa gba owo won lodo Ijoba. Pelu p le ru atako yi [illegible] bere.

## AFI FILA PA EKUN, OJO KAN SOSO NI IYI RE MO (APA 2.)

Lehin ti omo Ijoye Ojomu ti kuro lodo baba alagbara na, o mu fila na lori lo o di mo eru, to ba je fi ibujoko si oko won. O nda oko, o nşe ogbin, o si [illegible].

Lojo kan ni ilu daru ti gbogbo awon enia nsare jan, jan kakiri, eyi ti awi yi to iwon odun mejila lehin ti Ojomu ti ku tan. Awon ode nsure kira-kita, nitori awon yio ti bi nwon ti se. Irohin ti gbo kan wipe ako ekun kan wo ilu.

Ode ti o ba rope on gboju to lati pa ekun na ki o lo na owo ibon, ekun na ti kan lara, yio si fa lori nyagbe. Bi ekun yi ti npa omo de, beni o npa agba oro na di ki onilekun ma ti ilekun re, ko si enikan o le jade ni Ondo.

Awon babalawo ki fa wipe nigbati ara Ekun bayi ja wo ilu Ife nijosi, Orunmila lo mu ekun na. Ki oba si mu suru, Okunrin alagba kan mbo wa pa Ekun na. Nigbati Oba gbo bayi, o şeleri pe enikeni ti o ba le pa Ekun na, emi yio fi je oye Ojomu ilu Ondo.

Irohin Ekun yi bere si tan lo siwaju ati siwaju. Omo Oloye Ojomu gbo nipa irohin Ekun yi

(Wo yo ku loju ewe kerin)

## Omobinrin To Nko Ere Idaraya



Odomobinrin wundia ti a nwo yi nko bi a ti nse ere idaraya ti a fi eyege, oruko re ni Rosemary, omo odun metala, ilu oyinbo ni a bi [illegible], o si je omo ile Jamaica.

Okunrin ti a nwo ti o duro ti omobinrin na ni Thomas Swancott, o nşe apejuwe fun omobinrin na gegebi a ti ni lati şe ese ki a to fo igi da.




AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.


## Passing Out Parade and Presentation

### OF BATONS OF HONOUR BY

### THE INSPECTOR GENERAL OF POLICE

A Passing Out Parade will be held at 5.30 p.m. on Friday the 26th June, 1959, at the Southern Police College, Ikeja, when the Inspector-General of Police will present Batons of Honour to members of the Force.

A squad of Cadet sub-Inspectors who have completed their training will take part in this Parade.

By courtesy of the General Officer Commanding the Band and Drums of the Nigerian Military Forces will beat "RETREAT."

All friends of the Force are cordially invited to attend. Reservations for seats may be made by telephoning the Police College (Telephone No. 33326).

Spectators are requested to be in their seats by 5.15 p.m.

(L. O. EDET)
Acting Assistant Commissioner Of Police
for Inspector-General Of Police.

# Ayipada Olutoko Ijoba



Irohin ti a gbo ni wipe Dokita Nnamdi Azikiwe ti Işe Olotu ijoba Ila-Orun şe ayipada awọn Olutọkọ ijọba rẹ lori ipinlẹ Ijọba Ila-Orun, o pin ilẹ Iwọ-Orun si ẹya mejila labẹ Alakoso (Commisioner) kọkan ti o jẹ ọmọ ilu ti a pin fun u.

Awọn Alakoso (Commisioners) ẹya ipinlẹ kọkan si a to orukọ wọn wonyi: Oloye Onyiuke, Oloye Nwuke, Ọgbeni Apreala, Onwe Chime, Chidolue, Udonkim, Okafor, Ogon, Akpabio, Iwuagwu ati Dokita Obonna. Iṣẹ wọn yio si bẹrẹ lati ibẹrẹ oṣu June, 1959.

## Afese Pa Meje

Apa V

Afẹṣẹ pa meje bẹrẹ si lepa awọn omiran mẹtẹta lọ, titi o fi bẹrẹ si gbo bi nhanrun Ihanrun wọn na dabi igbati ojo nkun. Ogun ori igi kan ti o mbẹ nitosi ibiti awọn omiran na sun si.

O gbe okuta ti o kere o so o lu ọkan ninu awọn omiran na omiran ti okuta ba na ji omiran keji o kilọ fun pe, ki o maṣe tun gba oun leti mọ. Omiran keji binu o wipe tani o mba wi tabi ori ori rẹ fi ni eṣe? Omiran keta si pari ija fun wọn awọn tun sun lọ.

Ngbati orun tọ wọn la u, Afẹṣẹ pa meje tun gbe okuta omiran, o lẹ mọ ẹnikeji leti, o xare dide, o ji ẹnikeji rẹ, o wipe ṣe mo ti sọ fun ọ pe ko nṣe emi lo gba ọ leti, o ha fẹ pa mi ni bi? omiran akọkọ binu wipe Haba kini mọ tun fi se ọ ti iwọ ko jẹki nsun. Ibe ni awọn mejeji ba bẹrẹ si fọ mọ ara wọn awọn si fẹre ba ara wọn dimu ijakadi. Nwọn tun pẹtu si ara wọn ninu awọn dubulẹ nwọn sunlọ.

Afẹṣẹ pa meje jẹki orun wo won tara daradara o fi agbara gbe okuta keta, o sọ mo okan leti didide ti o dide ese lo gbele omiran keji ni eti ẹnikini dide o hu igi araba ẹnikeji hu igi ope, awon bere si fi na ara won ija na si po jojo

Nibii won gbe aja, awon tẹ omiran keta yọpọtu o si ku awọn meji ti o ku ba ara wọn ja titi ti ko fi si agbara kan ninu wọn mọ. Afẹṣẹ pa meje rin sunmọ ọdọ wọn, o fi ida rẹ bẹ awọn omiran mẹtẹta lori.

Nigbayi ni Afẹṣẹ pa meje bẹrẹ si mi hẹle-hẹlẹ, o ya ni odo o ha omi sori, o sọ fun oba pe on ti pa awọn omiran mẹtẹta. ki oba ranṣẹ lọ gbe ori wọn wa. Ẹ ma ka Iwe Irohin Eleti-Ọfẹ ẹ o gbọ nṣe keji ti ọba ran lati se

(Koiti pari)

## AFI FILA PA ẸKUN, ỌJỌ KAN ṢOṢO NI IYI RẸ MỌ (APA 2)

(O bere loju ewe kẹta) sugbon nitoripe, ko ni egbogi ko si ranti fila baba rẹ mọ. Gbogbo awon ọdẹ igboro ilu yii si aroko ni Ẹkun na fẹrẹ pa tan to bẹ ti ko si ọdẹ kan ti o jẹ daba lati lọ ko Ẹkun na loju.

Gbogbo awon ọdẹ ti o ku parojo si igberiko, Ẹkun papan se ode Ondo ti ko si ẹniti o le jade. Ọkan ninu awon ọdẹ lo ranti itan ti o ti gbọ lenu awon baba rẹ pe, awon ọdẹ ti o ba gboju a ma fi fila pa ekun.

E yiyi mu ki ọmọ Oloye Ọjọmu ranti fila ti o jogun lọdọ baba rẹ. O ta giri dide lẹsẹkanna, o wi fun awon ode ẹlẹgbẹ rẹ pe, loni dandan ni Ẹkun na yio ku.

Ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ ẹ o si ma gbo gẹgẹbi Afi fila pa ẹkun ti şe pa Ẹkun na.

(Koiti pari.)

## Won Ju Olugbimo Kan Sewon

GBOKO Ohun ti a gbọ ti awọn ro mọ Olugbimọ na lẹsẹ ni wipe on lo kọ aburo rẹ obinrin ki o fi ọkọ rẹ ti o nfẹ silẹ, ọkọ aburo rẹ na jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ N.P.C. o si jẹ Pataki kan ninu awọn Şẹkitẹri ijọba ibilẹ Gboko.

Ọgbẹni Tarka Olugbimọ ninu Igbimọ nla, (House of Representatives) ro ẹjo tirẹ bayi wipe, ni ọjọ kọkanlelogun oşu May, ti on pada de lati ilu Kaduna, ile ni on ba aburo on ati nigbati on şe abere kilofaa ti o fi wa sile on, o si dahun pe on pelu oko on ni gbolohun asọ ni.

Mo şe arọwa fun pe ki o pada lo sile ọkọ rẹ, bi ko ba si le şe bẹ, ki o ko ẹru rẹ lọ si ile baba rẹ.

Ọgbẹni Gregory ti o şe adajo agba lojo na, dahun pe on ko gba gbogbo ọrọ ti o so gbo lo ba ni ki Ogbeni Tarko lo si ẹwon osu mefa. Nigbati nwon de gbangba ode Tarka ba awon enia tire soro wipe ki nwon şe jẹjẹ, on ko gba idajo ti nwon da fun on yen, nitorina onyio gbe ẹjo na lo si kotu arotunro, nwon si gba iduro fun u.

## Alabojuto Ijoba Ibile Si Ile Olopa Titun

ABEOKUTA. Ijoba Iwọ-Orun fi ẹgba Poun ko ile işẹ fun awon Olopa ibilẹ ni ilu Odẹda ati ni Obafẹmi.

Ọgbẹni D. S. D. Adegbenro fi iyin fun awon olopa Egbe, wipe, nwon şişẹ daradara işẹ won ko nşe eyiti a le fi owo ro ti

Nisiri iru awon kotu olopa bayi sile Egba je ilosiwaju ise olopa ijoba ibile.

E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE

LỌSỌSẸ, O KUN FUN IROHIN ALADUN

## Ilu Ghana Yio Gbe Owo Tire Jade

ACCRA. Irohin kan wa wipe Ijọba ilẹ Ghana, ti Dr Kwame Nkrumah jẹ Olotu rẹ (Prime Minister) ti gbe ikede kan jade nilu Aganyin wipe:- "Ẹ ma na'wo Ghana ni Ghana" ati wipe ki Olukuluku enia ko gbogbo owo ati iwe owo atijọ ti o ba wa lọwọ wọn wa parọ ki o toto ọjọ kini oṣu July, 1959, ti owo Ghana yio jade fun lilo.

Ọpọlọpọ iwe ikede bi ẹgba-gbeje ni a gbọ pe Ijọba lẹ mọ ode kakiri ilu, bi o ba di ẹhin ibẹrẹ osu July owo atijọ ko ni jẹ nina nilẹ Ghana mọ ṣugbọn nwọn yio ma parọ rẹ fun awọn enia ti o ba ni lọwọ ti o si mu wa.

## BABA ẸGBẸ UNION KU LOJIJI

IBADAN. A gbọ wipe ọkunrin kan ti o njẹ A.C. Kaniku, Baba ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ Tobacco African Workers Union nibiti o gbe nsọrọ lọwọ ni oyi gbe lojiji o si gba ibẹ yọ si ọrun alakeji aremabọ.

Awọn ọlọpa ti bẹrẹ si fi imu finlẹ ṣe iwadi iku ti o pa Baba ẹgbẹ na. A gbọ pe Baba ẹgbẹ na, ọgbọn pọun lo ngba ni oṣoṣu. Nwọn gbe oku rẹ lọ sile Alaisan fun ayẹwo.

**Baba ẹgbẹ na dagba to ẹni odun mejidilogoji ofi Iyawo rẹ silẹ ati omo meji.**

**Lowo Iku ojiji Oluwa rere gba wa.**


## Kere o !

**A ni orisirisi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin obinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.**

**J. A. AJAO BROTHER MEDICINE STORES**

**7 Egerton Road Lagos**




## E Q LAJA TUN NLO S'WAJU OBA ILU OYINBO

Ogbeni Gabriel Oluwole Laja, enti awon olopa ba ro ejo fun enia wipe on pelu enikan lu Ogbeni Okupe ti o nje Agbonmagbe ni ijiba ti nwon si titori re ju si ewon odun meta fun enia na.

Sugbon Ogbeni yi ti o ti nse ise ni ogba Reluwe ti o si je gbajumo enia dahun wipe on ko jebi oro na ati pe on fe gbe ejo on lo siwaju oba ilu Oyinbo (Privy Council) nibiti ofin ko mo eni-owo ti awon ogunna gbomgbo tori won ti pa fun ofin gbe ajoko si.

A si gbo wipe ijoba Gesi yio tun ejo na da. bi o ba sese ni inu osu July. Eniti yio se agbejoro fun Ogbeni Laja ni Ogbeni D.N. Pritt Q.C. ati Loya ilu London kan ti o nje S.N. Bernstein.

## Ogbeni Madarikan Di Olori Alafisun Ijoba Iwo-Orun

EKO. irohin de odo wa wipe Ogbeni Charles Olusoji Madarikan, eni ti o ti mbe ni ipo akowe Adajo labe Ijoba apapose nilu Eko ni nwon gbe ga siwaju, ti nwon si gbe si ipo Olori Alafisun fun ijoba Iwo-orun, yio si bere ise re lati ibere osu July 1959.

Itan ni ba soki ti agbo nipa Ogbeni Madarikan o gba oye loya ni Lincoln's Inn lodun 1948 o bere ise Amofin nile Nigeria ninu osu February 1949, gegebi Alafisun kekere, kerekere o di Alafisun agba, ninu osu March 1956.

Ninu osu July 1957 lo se ise nipo Olori Alafisun (Solicitor General)lodun na lodi akowe ofin fun Ijoba ile Kamerun, ki o to wa di akowe Adajo ninu osu March 1958.

Die ninu awon ejo ti o so o di olokiki enia ni ejo Bisiriyu Apalara ti o di obun ti nwon ni lati yegi fun awon enia Alawo Opa mokanla. O tun se asoju Ijoba nigbati nwon nse ejo ile Diobu ni agbegbe Ila-Orun

Lehinna, o gba ebun "Apopupa" kan lowo Ogbeni Frank Gahan, okan ninu awon ogunna gbomgbo ninu ofin Gesi, gegebi ebun ti a nfifun eni ti o ba ja fafa ninu ofin Gesi.

## Oyinbo Onisowo Fi Aga Ta Okunowo Lore

IJEBU—ODE Olotu ile ise oyinbo Onisowo Faranse CFAO, ti nwon npe ni Ogbeni G Lathene lo fi aga igunwa kan ta Oloye E.O Okunowo lore loruko egbe Onisowo Franse na. Nwon fi ebun yi ta a lore fun mimo riri ibasepo won pelu re gegebi Olotu na ti se irohin re

Oloye Okunowo joko ya aworan lori aga na, Iya re ya aworan pelu aga na, Miss Nigeria ti odun 1958 na joko le lori o ya aworan,




"DE FACTO"

BREAD



THE BEST IN NIGERIA MARKET

KNOWN FOR ITS NUTRITIVE QUALITY


## MUSULUMI GBE KIRI-YO NIYAWO NI SOSI AGUDA

PARIS. Odomokunrin Imale kan ara ilu Algeria, lo gbe omo Kiriyo kan ti Ijo Aguda ni iyawo arede ninu Sosi Aguda ojo iyawo yi nlnringidin fun toko tiyawo.

Ni gere ti won pari igbeyawo tan ninu Sosi Aguda na ni oko iyawo ti o je Imale wa duro lenu ona Sosi Aguda beni okan ninu awon ti njagun nilu na l, wo ta ibon fun oko iyawo na, nwon si pa.

A gbo wipe lati odo olori ijo Aguda ni nwon ti gba ase wa lati se igbeyawo na ninu ile isin awon Aguda.





Buy the Railway PUBLIC TIME TABLE

at 3d from your STATIONMASTER

★ Travel by TRAIN and RELAX ★



E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE

LOSOSE. O KUN FUN IROHIN ALADUN


Printed & Published By The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23378